# EKO AKETE.

## IWE IROHIN OSOSE.

VOL: I. NO. 15. SATURDAY, OCTOBER 21, 1922. THREEPENCE.

*Editor:*—ADEOYE DENIGA,

*Office:* 24, Williams Street,

P.O. Box 286

Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Odun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranse si *Editor*

## GBOHUN-GBOHUN.

### MA DA MI RO IKU MA A BỌ, NGO BA Ọ LỌ L' AYỌ.

A kẹdun iku iya Alufa Ologbe Ẹni-Ọwọ JOSEPH SUBERU FANIMOKUN, t' o ṣẹlẹ ni ọsẹ t' o kọja; a si gbe sin ni Itẹ Ikoyi: Ẹnyin ọkawe wa yio ranti pe ọmọ rẹ na, ẹniti okiki rẹ bi Ọga-Agba Ile-Iwe-Giga ti C.M.S. nibi, kolẹgbẹ ni akoko tirẹ, ṣalaisi ninu oṣu *March*, ọdun *1920*, ni Agege.

K' Oluwa gbe awọn ẹni rẹ yi s' afẹfẹ rere,

### EGUN NLA TI NFỌHUN BI ENIA.

Ẹni-Ọwọ S. A. COKER, Alabojuto, ṣe Iwasu-Akanṣe kan ni ede Gẹsi ni Ile-isin Ijọ *Bethel* ni alẹ ọsẹ to kọja, ni iranti ọdun kọkanlelogun ti a ti fi Idi Ijọ na kalẹ: a gbọ pe Ẹni-Ọwọ yi "fọ'gi" ninu iwasu na lọpọlọpọ.

A ni 'reti pe a o tẹ ẹ fun kika gbogbo enia laipẹ

### AFUN-RURU, ALA ORIṢA!!!

*Bishop* OLUWOLE ṣe isin Imulọkanle ninu Igbagbọ fun awọn kan ni Ile-Isin *Breadfruit* ni ãrọ ọjọ ọsẹ to kọja.

## BẸ, BẸ, NI K' A MA RI.

Inu wa dun lati gbọ pe a gba Ọgbẹni kan ti o njẹ C. B. Kuforiji, Oloye B.A. si iṣẹ lati jẹ ọkan ninu awọn Olukọ awọn ọmọde, ni Ilé-Iwe Giga ti Eko (Eko *Boys' High School*): a ba Ẹni-Ọwọ W. B. Euba, Ọga-Agba Ile-Iwe na, ati Ọgbẹni O. Edward Roberts, Igbakeji rẹ ati awọn Olukọ t' o ku n'bẹ yọ si ilọsiwaju iṣẹ wọn yi.

---

## OJOJO NṢ' OGUN ARA OGUN KO LE.

A gbọ pe oyinbo Ọgbẹni A. R. C. Larbode, Aṣoju Gomina, ni ilu Badagry ṣaisan, a si gbe e lati ẹnu iṣẹ rẹ wa si Ile-Alarun nihin ni ọsẹ ọhun.

---

## ISIN ATI AṢA ILẸ WA.

Olukuluku Orilẹ-ede ni Ọlọrun fun ni isin tirẹ ati aṣa ti yio ba ilu na l' ara mu; awọn oyinbo ni tiwọn, bẹ si ni awa enia dudu pẹlu; ṣugbọn o dabi ẹnipe awa gẹgẹ bi enia dudu, pãpã awọn ti Ọlọrun fun l' aye ati mọ iwe ati lati ri oye diẹ nipa ti awọn oyinbo, o njẹ ohun itiju fun wọn lati sin Ọlọrun l' ọna ti awọn Baba wa ati lati ma lo o gẹgẹ bi aṣa ilẹ wa. Nwọn gbagbe pe awọn oyinbo tabi ilu miran l' orilẹ-aiye, nṣe ni nwọn ntun isin ati aṣa wọn ṣe titi o fi ri bi o ti ri loni yi, nwọn si mu u l' ọna ti yio ba ara wọn mu.

Kini ha mu itiju ba awọn enia dudu ti o mọ iwe lati ma lo, tabi lati sin gẹgẹ bi aṣe ilẹ wọn, ohun ti o mu eyi wa ni pataki ni pe, nigbati oyinbo ma bẹrẹ si kọ wa ni iwe nihin, awọn ti a ti ta danu gẹgẹ bi ẹru, awọn li a kọ fun ni anfani yi' awọn oyinbo fun wọn ni Orukọ ilu wọn. Aṣa ilu wọn ati Isin wọn pẹlu, nipa eyi, iwa ti o ti mọ wọn l' ara l' oko ẹru ko ṣe ja ju ṣilẹ, eyi si jẹ ki aṣa alaṣa ati isin-onisin ki ọ wu wọn ju ti ilẹ wọn lọ.

Ni ilu Aganyin ibajẹ yi ko pọ to ti apa iha ti wa nihin, pãpã nipa ti aṣa ilu ẹni nitori ni ilu wọn, ọpọlọpọ ninu awọn ti o mọ iwe, ibãṣe Dokita tabi Lọya, l' o njo ijo ilu wọn, ti nwọn si nba ilu wọn ṣe ọdun ilẹ wọn; ẹniti o ba nka Iwe-Irohin ilu wọn ti a npe ni "*Gold Coast Leader*" tabi ti ilu Oyinbo ti a npe ni "*West Africa*" yio ma ri ohun ti a sọ yi ninu rẹ, ṣugbọn niti wa nihin, ohun gbogbo ni keferi, ohun gbogbo ni o rẹlẹ, afi ti oyinbo ṣa, bẹni ilu ti o ba wa ti nkan tire ko kun loju, ko le niyi nibibibi.

Ilaju ti oyinbo ti o jẹ ohun ti gbogbo wa nnaga si, bi a ba wo daradara, eyi ti o fi san ju tiwa lọ ko dabi alara, ẹniti o ba nka Iwe-Irohin wọn ni yio ri eyi, oniruru iwa l' o kun ibẹ, iwa alainitiju, iwa ọdaju, ipania loju ko ju ẹgbin oniruru, bẹni aṣa wọn l' a nfẹ lati ma koyi, nigbati a ba si ju gbogbo tiwa nu, ti a mu tiwọn, irufẹ iyọnu ati lasingbo ti o nfi ojojumọ wa ni ilu wọn, on ha kọ ni a o ko wa ilẹ wa; ohun pupọ ni o wa ninu isin wa ati aṣa wa ti o dara pupọ, ti o si jẹ pe ti a ba bẹrẹ si ṣe, dajudaju oyinbo pãpã a tun ma jowu lati ma kọ ẹkọ ninu rẹ ni. Ṣugbọn nigbati a ba ko wọn junnu, kinni a o ri lati fi ma ṣogo gẹgẹ bi orilẹ-ede "Cnigba l' o npe igba rẹ ni akikaragba, ki a to ma ba a fi ko ilẹ."

Ọpọlọpọ wa l' o ti ngbọ pe ni lailai, awọn Baba nla wa le ji oku ti o ba ṣẹṣẹ ku ti a ko bai ti sukun rẹ tabi ki nwọn lo afẹ-iri nigbati ẹwu ba ka wọn mọ; nigbati awọn oyinbo Onigbagbọ de nkọ, pẹlu awọn ẹru ti a ti ta lọ ti nwọn jẹ Onigbagbọ, gbogbo rẹ kọ ni nwọn ha ti jẹki awọn Baba wa ko sọnu? ohun pataki ti a le ma fi ṣe ọkọnrin nigbati iya ti o pọju ba njẹ ni.

Ẹ jẹ ki a mnra lati bẹrẹ si wadi ohun ijinlẹ ti ilẹ wa, awọn oyinbo pãpã ti a nfẹ ma f' arawẹ, ki iṣe bi nwọn ti wa loni yi ni nwọn wa ni ọgọrun ọdun t' o kọja, nwọn ko joko lati ma f' arawe nikan tabi lati ma ko aṣa-alaṣa lawadi rẹ, ṣugbọn awọn pãpã nṣafẹri ohun ti o pamọ, eyiyi l' o si mu wọn tẹ siwaju ninu ohun gbogbo.

Gbogbo wa l' o ngbọ ti awọn Baba wa nsọ wipe Ile-ifẹ ni ọgba Eden, ati pe nkan iyanu ati oniruru nkan Ṣeranwo ti o jẹ ti iṣẹdalẹ aiye l' o wa nibẹ, ninu awọn ti Ọlọrun, fun ni oye iwe ninu wa l' o gbidanwo ati lọ wo ohun wọnyi bi otọ ni, ati lati gbidanwo pe ki a tilẹ kọ iṣẹdalẹ aiye gẹgẹ bi awọn Baba wa ti sọ; bẹni a nbinu nigbati oyinbo onipo nla kan sọ pe a ki nṣe orilẹ-ede, ati pe isin ti a nsin ti oyinbo ni, eyi ko ha fẹrẹ jẹ otọ bi? ami orilẹ-ede da lãrin wa, nigbati awọn ti o mọ ede oyinbo ati aṣa wọn nfi ẹnu ṣata eyi ti o jẹ ti ilu wa nihin? oyinbo kan ti a npe ni *Captain* WYNDHAM, on l' o ṣẹṣẹ ṣe iwe nipa iṣẹdalẹ aiye gẹgẹ bi a ti sọ ni Ile Ifẹ, bẹni ogunlọgọ awọn enia wa ti o mọ iwe l' o wa, ṣugbọn irufẹ iṣẹ daradara bayi ko si l' ọkan wọn

Irufẹ iwa iṣata ohun ti ilu ẹni, ko le gbe wa ga bikoṣe irẹsilẹ, ẹ jẹ ki a mura lati bẹrẹ si ma gbe ohun tiwa ga, ki a si ma wadi aṣa ati isin ilẹ wa dada, ki a ma joko ti awọn ti o jẹ pe nwọn ko le ri ohun ti o dara, niti enia dudu, gbogbo rẹ ṣa ibọriṣa ni, nwọn gbagbe pe ki iṣe isin Igbagbọ tabi ti Imale nikan l' o le gbe orilẹ-ede ga, sisin Ọlọrun l' ọna miran ngbe orilẹ-ede soke pẹlu, ẹ wo awọn ara ilu *Japan*, nwọn ki iṣé Onigbagbọ tabi Imale, sibẹsibẹ, ninu alagbara marun ti ó wa l' aiye ni nwọn wa, ko si si ilu kan labẹ ọrun ti o jẹ da 'ka wọn kọ.

FANOKUN.

---

## "IJỌ A BA PADE L' HIN ỌGBA KUNGU A FỌ L' ẸHIN ỌGBA."

Awọn Ẹgbẹ Kokoro si nfi Ọlọrun ṣe iya, ti Ijọ ọmọ ibilẹ Eleto. (*Young-women Providence Society*) yio tun ere igbadun wọn ṣe ninu ile Afariogun l' ẹhingbẹti, (*Glover Memorial Hall*) ni ijọ *Wednesday* kini ni oṣu *November*, 1922. A o si jo ijo Oyinbo ni pari ere na, (*Fancy dress ball*) awọn ọdọmọ-binrin omujo yio pọ nibẹ A ki o si gba hauka enia kan si ibi ijo na

Alao, ọjọ na yio tiri? Ayinde, ngo ṣe bi Balogun Kara nile Ilọrin: jọwọ gba mi ni 'tẹ mo ri ara ti ngo fi owo da, o di 'jọ na.

## PREACHERS FOR TO-MORROW.

### AWỌN ONIWASU ỌLA.

---

### ROMAN CATHOLIC

Masses will be sung by Priests appointed.

Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi.

| (Morning.) | Masses Isin Arọ. |
|---|---|
| 6.30—7.30 | 8.30—8.30 |
| 7.30—8.30 | 93.0—10.30. |

| (Evening.) | Masses (Benediction) Isin Ibukun. |
|---|---|
| 4.45—5.30 | 6.45—7.30. |

### ANGLICAN

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m.—Christ Church | Rt. Rev. Bishop Oluwọle |
| 6.30 p.m. | Rev. H. V. E. Johnson |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—St. Paul's (Breadfruit) | Ven Archdeacon T. A. J Ogunbiyi |
| 9. a.m.—St. John's (Arọlọya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 9 a.m. 4 p.m.—St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero) | Rev. S. J. Gansallo. |
| 9 a.m.—St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |

### WESLEYAN

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m.—Tinubu | Rev H W. Stacey |
| 7 p.m. | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m.—Ereko | Rev. D. A. Beckley |
| 7 p.m. | Rev. S. A. Pearse |
| 10.30 a.m.—Olowogbowo | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 7 p.m. | Rev. E E. Williams |
| 10.30 a.m.—Ọbun Eko | Bro. N. A. Thompson |
| 7 p.m. | ,, E. Adeniyi Oluwa |

### AFRICAN (COMMUNION)

| | |
|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Rev. J. F. Ogunko |
| 7 p.m. | Rev. Superintendent G. A. Oke |
| 9 a.m.—Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 4 p.m. | do. do. |
| 9 a.m.—Bethel | Rev. E. A. Akiola |
| 6.30 p.m. | Rev. I O. Oyekunle |
| 10.30 a.m.—African Methodist | Bro. L. A. Randle |
| 4.30 p.m. | Bro. S. T. Zannu |
| 9 a.m.—Ararọmi Church | Rev. A. A. Puddicombe |
| 4 p.m. | Bro. J. Adewuyi |

### EBENEZER

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | Bro. John Apena |

### St. STEPHEN'S (EPETEDO.)

| | |
|---|---|
| 9. a.m | Very Rev. J G. Campbell |
| 4 p.m. (*Ordination Service*) | Rev. Alfred C. Braide |

### BROTHERHOOD.

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m.—Ilupesi | Bro. S. Coleman Daniel |
| 7 p.m. ,, | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

### AHMADIA.

| | |
|---|---|
| 5.30 p.m.—Open Air Service (Vincent Street.) | Prof. A. R. Nayyar |

### COLONIAL CHURCH (ODAN)

A nyan Awọn Alufa si Ile Isin yi lọsọsẹ.

# EKO AKETE.

EKO, SATURDAY OCTOBER, 21, 1922.

———

## ỌKAN ṢOṢO ARABA T' ẸGBA ỌṢUNṢUN.

O YẸ o si tọ gidigidi fun ti olori ti elesi wa ni ilẹ yi lati dupẹ at' ọkan wa fun ẸNI-ỌWỌ ARCHDEACON T. A. J. OGUNBIYI Ojiṣẹ-Ọlọrun, ti Ijọ *Breadfruit* fun apẹrẹ rere to fi lelẹ ti ki yi o parẹ lailai, nipati ayan to ṣe lati fi ẹyẹ fun Iya-Afin MARY AKIFENWA Ọga-olukọ obinrin ti Ile-Iwe awọn ọmọ wẹwẹ ni *Breadfruit*, ti o wa labẹ Ẹni-ọwọ yi, nipa Isin-Idupẹ ti o ṣe fun u nile Isin na ni agogo mẹrin-abọ ọjọ *Friday* ọsẹ to kọja NIGBATI IYA-AFIN NA DI ENI ODUN MEDOGBON NINU iṣẹ rẹ: o da wa loju, a ko si bomi sẹnu sọpe eyi lo jẹ igba kinni ti a ṣe ẹyẹ gba-ngba irufẹ eyi fun ẹnikẹni ni Ile-Iwe yi. Irohin ti a ri ka ninu ninu ọkan tabi meji ninu awọn Iwe-irohin nibi, niwọn oṣu diẹ sẹhin. pe ki gbogbo awọn ẹmọ Ile-Iwe na, to ti jade lọkunrin lobinrin gi arajo, lati rọ ọna ti wọn yi o gba lati ṣe ẹyẹ yi fun MRS. MARY AKIFENWA, ko ṣẹhin, ENI-ỌWỌ yi: ọkan ẹnikẹni to gbọ Iwasu rẹ ni ọjọ ti a wi yi, kole ṣai gbọgbẹ fun ikẹdun ti Ẹni-ọwọ yi ṣe pe irufẹ ohun ribiribi bayi ko wọpọ larin wa nibi: ṣugbọn gẹgẹ bi o ti bẹrẹ yi, a ni ireti pe, l' agbara BABA, ki yio parẹ: orin ti a kọ, adura ti a gba, ati Iwasu ti a ṣe ni 'jọna fun Iya-Afin yi, dabi ẹnipe A ṢẸṢẸ GBE E NI IYAWO NI, eyi si mu ki ori wa wu lọpọlọpọ tobẹ ti a fi sọkuu ayọ. A tanmọ pe gbogbo awọn t' o lọ si Isin ẹyẹ yi, pāpā awọn obinrin ni yio ri ẹkọ iyebiye kọ ninu rẹ.

Lẹhin igbati a fi Ile-Isin silẹ, a lọ si gbangan Ile-iwe na, nihin ni awọn obinrin agba Ijọ ti MAMMY WILLIAMS jẹ aṣaju fun, ta Iya-afin yi ni Ọrẹ Bibeli ati owo, nwọn si sure fun u: awọn Olukọ toku, ẹwẹ, si ta a ni ọrẹ owo, nwọn si fun u ni Iwe-Iyẹsi; a ṣe gbogbo ẹyẹ yi niwaju Ẹni-ọwọ na pẹlu awọn Isangbe rẹ, awọn Ọgbẹni A. E. NORMAN-WILLIAMS ati WILLIAM GEORGE ati ọgọrọ enia t' o wa woran.

Lẹhin eyi, a wi fun Iya-afin na pe ko ṣi awọn Aworan rẹ ti a ya gadagbagadagba si ọna meji, (*Enlarged Photograph of herself*) eyiti gbogbo awọn ọmọ-ile-iwe t' o wa nibẹ nisisiyi dawo si: nigbati o ṣi awọn Aworan na, ariwo sọ lala, eyi si ni a fi pari ayọ ati ẹyẹ ọjọ na. A o fi ọkan ninu Aworan na kọ si Ile Nla ati ekeji si Ile Kekekere Ile iwe na.

A sọ pe nigbati o ba ṣe, awọn Ọmọ Ile-iwe toku ti nwọn ti jade yio tubọ gbarajọ lati ṣe ẹyẹ tiwọn gẹgẹ bi o ba ti tọ. A mọ pe bi Ẹni-Ọwọ ARCHDEACON OGUNBIYI ko ba pẹkẹ lu ọjọ bi eyi, a ko ni gbọ "kuku:" nitorina ni o ṣe yẹ lati sọpẹ lọwọ rẹ fun Iṣẹ AIMOTIARA-ENI-NIKAN t' o ṣe l' ọjọ na. Nitori idi eyi ni a fi ki i ni Ọkan-ṣoṣo Araba-t' Ẹgba-Ọṣunṣun. Lẹkan si, a tun ba Arabinrin na yọ si pipe ti gbogbo awọn ọmọ rẹ pe e ni Alabukun fun gẹgẹ bi ọrọ t' o wa ninu Iwe Mimọ (Iwe Owe Ori *31*, Ẹsẹ *28*) ti a fi wasu fun u ni ọjọ na. AYỌ AB'ARA TIN-NTIN.

## IGBẸ L' OWO WA.

### EKURỌ.

Bi awọn oyinbo Ile-ọ̀wọ̀ wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

| | |
|---|---|
| Ẹgbẹ Idapọ-Ọ̀wọ̀ (A. & E. T. A.) | £11 fun *ton* kan |
| Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co,) | bakanna |
| Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores) | do |
| Miller | do |

### EPO.

£21 ni gbogbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a darukọ wọnyi gba *ton* kan.

### COCOA.

Lati £25 de £27 fun *ton* kan bakanna.

## KABIYESI! ALAKE ỌBA ẸGBA. Ẹ KU AGBA. Ẹ KU INAWO ỌJỌ

Ni *Saturday* kẹta ọhun, ijọ kẹtalelogun oṣu *September* tio kọja, Alake Adẹmọla II ṣe ọhun ara l'Abẹokuta o siṣe gudugudu meje ni iranti adọta dun ọjọ ibi rẹ l'aiye. Ọpọlọpọ Sanmọri oyinbo atata ati gbajumọ ọlọla enia dudu ni a pe sibi ase na. Ki o to to agogo meje pẹlu abọ ti a ni lati da sẹria fun onjẹ nla yi, ina omwaya (*Electrict light*) nṣe bi arira n'ita Ọba; nwọn ri wẹnrenkẹnṣẹn, nwọn si mọlẹ tobẹ gẹ ti gbogbo okunkun ti mbẹ l'agbegbe ibẹ fi f' esẹ fẹ ẹ. Kai! Ina wole okunkun parada. Gbangba d'ẹkun, kedere bẹ wo.

Eni tere, eji tere, ẹṣẹ awọn bọrọkini ti a pe sibi ase njọ; nigbati osi to iwọn agogo mẹjọ gbogbo ile kun ṣọṣọ. Major W. Birrel Gray, Captain F. C. Royce, Dr. G. B. Walker, Ọgbẹni C. B. Coleman, B. J. A. Mathews, Percy F. Herbert, Thorburn, A. W. T. Moorman, George Twigg, Stanley Griffiths, Biṣọpu Oluwọle ati Dr. Ladipọ Oluwọle ọmọ rẹ, Balogun Ṣowẹmimọ, Jagunna Adegboyega Ẹdun, Paadi J. A. Coquard, Paadi Grando, Alufa S. C. Pinnock, Alufa S. A. Delumọ, Dr. A. Ladapọ Oluwọle, Ọgbẹni J. B. Majẹkodunmi, awọn Amọfin (ki nṣe ti Farisi) amofin Alakija mejeji, Ọgbẹni Timothy Kester ọkọnrin jẹjẹ abija kikan, ati olori Dr. enia dudu Oguntọla Ṣapara wa ninu awọn onipo ati ọlọla ti ko farasin mbẹ.

Awọn ẹgbẹ oni kakaki goje (*Musical Band*) wa mbẹ pẹlu lati ṣe ariya; nwọn si fun t'ijọ ti wọn ko ni r'aye ninu fere l'alẹ ijọ na. Gbogbo rẹ ndun yungba. Bi eyi to ni ohun goro ti nhan bi irẹ, bẹni olohun konkọ nfẹ fo o: ẹniti o nṣan omele ni ki nwọn fi le on l'ori te. Mo ngbọ woroworo, mo si tun ngbọ Dẹm! Dẹm!! Dẹm!!!

Ọjọ ko sa ngun ko ma k'ọla. Akoko lati jẹun de. O wa ku sọwọ oyinbo Ọgbẹni Ramu, (*Rahm*) iyawo Apọn (*Bachelors*) Alaseta ọbẹ, ti Ọba Alake fi owo gbe dide lati Eko wa si Abẹokuta ki o wa se onjẹ adidun oyinbo fun awọn alapejẹ rẹ. Aṣọ ori tabili funfun bi ojo didi, ṣibi, fọku agunjẹ oniga mẹta ati ọbẹ ndan bi fadaka; oriṣirisi awo ntaka si ara wọn. Laisi amani, Ọba nikan lo tó ehin erin fọn.

Oyinbo Ọgbẹni Ramu pẹlu awọn emọ iṣẹ rẹ bẹrẹ si fun wa l'onjẹ. Ka to jẹ ọkan tan orisi miran ti gba ipo rẹ. Kosi Iyan, kosi Ẹkọ, kosi Amọla, fufu tabi ẹba gari olowoyọ kosi nibẹ pẹlu, Ṣugbọn onjẹ oyinbo bi *Horsd Oruves, Mock Turtle Soup, Fresh Salmon, Sauce Mayonnaise, Cutlets, Green Salad, Baked Potatos, Coffee*, Tolotolo ati itan ẹlẹdẹ dindin ya yẹyẹ sibẹ. Ajẹti ni gbogbo wọn. Nigbati akoko jijẹ kọja ti mimu gba ipo rẹ. Kosi to iṣẹju melo kan oku igo ti sun bẹrẹbẹ sori tabili. Ṣampeni (*Champagne*) nṣan bi agbara awọn aburo rẹ nrọ bi ojo. Nigbati awọn Ọmu s' oro f' ọti, awọn Paadi alagbada funfun ati awọn alufa ti o di kọla kẹhin s'aiye (*clerical collars*) nwo wọn lawo mọju. Anu wa ṣe mi pupọ l'alẹ ijọ na wipe oju koro ko le pa oju koro jẹ.

Lẹhin ti a jẹ, ti a mu tan, akoko na wa a de fun awọn olohun iyọ, awọn ajisọ didun lati fi ẹbun wọn han. O bẹrẹ lori *Resident* oyinbo, lẹhinna o kan Alake papa ọmọ Erin jogun ọla; kabiyesi Ọkanṣoṣo Ajanaku to nmigbẹ kiji kiji. Bi ọla rẹ ti tobi to bẹni Gẹsi ẹnu rẹ yọ to. Kẹrẹkẹrẹ o yi kan Adegboyega Ẹdun, ọkunrin ti a fi nṣepe ọkunrin, O le babalawo ko duro ko 'fa, a pa pa ko ku, a le le ko lọ, iku ti nsọ ede Gẹsi, O ro fun pupọ lalẹ ijọ na, on nikanṣoṣo fẹrẹ fi gbogbo ọrọ sọ tan. Gẹsi bọọlibọọli tan ninu Dikṣonari. Nigbati o ṣe Bishop Oluwọle dide, agbalagba ẹni ọwọ julọ, arẹwa ọkunrin to dabi wundia, ọjọgbọn ninu Ẹkọ oyinbo, oloye nla D.D. eyiti itumọ rẹ njẹ Dr. ọfu Difiniti, ọrọ rẹ wọ ni leti lọpọlọpọ, osi sọ kobakungbe ọrọ nipa ọna yẹyẹ ti ọpọlọpọ, tọkọ taya Ẹgba ni kọ ara wọn silẹ ni Abẹokuta. Ọgbẹni J. B. Majẹkodumi, ọtun Ẹgba sọrọ niba ṣoki. Dr. A. Ladapọ Oluwọle, Paadi Alufa Grando, Alufa J. B. Lawson, Balogun Ṣowẹmimọ, Oyinbo George Twigg, Stanley Griffiths, Alufa Pinnock, Oyinbo Percy Herbert, Ọgbẹni E. S. Ikoli ati Amofin Alakija ti o sọrọ gbẹhin sọ oju abẹ niko, o gbadura kolẹgbẹ kan.

Lẹhin eyi ta fi ile Ọba Alake silẹ ni agogo mejila oru kọja iṣẹju mẹdogun. Gbogbo ọrọ ti nwọn sọ lori tabili nijọ na, ti enia funfun ati ti enia dudu ni mo kọ silẹ patapata ni ede oyinbo. Ẹnyin yio si ma ri wọn ka ninu iwe irohin ti a npe ni *African Messenger*.

O le diẹ ni adọta ọdun loni ti a bi Alake Adẹmọla II l'afin Ọba ni Abẹokuta September 20, 1872. Baba rẹ ni Adẹmọla to jọba Alake ni Novembor 20, 1869. Orukọ iya rẹ agba a ma jẹ Tẹnidade ọmọ ọba Jibodu Alake, ọkan ninu awọn Ọba to jẹ lori Ẹgba l'orile. Ni kekere, Adẹmọla to wa lori oye yi kọ ẹkọ n'ile iwe *Saint Peter*, Abẹokuta, lẹhin na o wa pari ẹkọ rẹ ni "Eko Akete," ile ọgbọn.

Ni ọdun kẹrinlelọgbọn ọhun 1888, o bẹrẹ si kọ iṣẹ atẹwe (*Printer*) labẹ Daddy J. B. Benjamin ologbe. Ọdun meji lẹhin eyi, ni 1890, o lọ ṣe ọga awọn atẹwe labẹ oniwe irohin, *Lagos Weekly Record*, Daddy J. P. Jackson ologbe ẹni ti ọmọ

rẹ Ọgbẹni Tommy Jackson rọpo rẹ nisisiyi. Ni ọdun kẹrinlelogun *1898*, a yan Ademọla si ẹgbẹ Igbimọ t'o nṣe ilu Ẹgba, o si sa gbogbo ipa rẹ fun ire ilu rẹ. Ọpọlọpọ igba l'o nfi aya ran iṣoro, to si nfi ọgbọn ẹlẹ ati iwa pẹlẹ dubu ọpọlọpọ ija igboro tiba ṣẹlẹ l' Abẹokuta nitori ede koyede ati arankan to wa larin ilu. Ni ọdun kejidilogun to kọja, *1904*. o ba Gbadebọ Alake, Adegboyega Ẹdun, ati ologbe R. B. Blaze lọ silu oyinbo; o si ri anfani ati ba Ọba Edward VII ologbe sọrọ ni afin ọba, *Buckingham palace*, London. L' ọjọ na ni a tọka rẹ pe on ni yio rọpo Gbadebọ bi Alake.

Ni ọdun kẹta, *1909*, tẹmbẹlẹknn jẹ ko fi ilu silẹ, o si lọ da oko ramuramu si Ọba nitosi Abẹokuta. Nibẹ o gbin *cocoa*, *coffee*, obi, iṣu, agbado ati ohun gbogbo ti o nsọ agbẹ d'olowo. O ṣe ọdun mọkanla gbako nibẹ. O si pada wa ile ni ibẹrẹ ọdun *1920*, nigbati a fi ilu ati ijo pade rẹ.

O de kopẹ titan de si Gbadebọ; gbogbo ilu si f'ohun ṣọkan lati fi Ladapọ Ademọla jẹ Alake ni ijọ kẹfa oṣu *July*, *1920*. Laifagun lọ titi o wọ Ipebi n'ijọ kẹtadilogun oṣu kanna, o ṣe isanye n'ijọ kẹrinlelogun oṣu kan na, o wa gb' Ade ni ọjọ kẹtadilọn oṣu *September 1920*. Aye gbọ ọrun mọ.

Dlẹ ti a sọ ninu itan Alake yi fihan ni gbangba pe, iṣẹ Ọlọrun awamaridi ni, abinu ẹni ko si le pa kadara da.

Abọ mi ni yio, kabiyesi! K'ẹmi Ọba ko gun. Lagbara Odumare Ladapọ Ademọla II a a gbo a a tọ. Ninu ofi i, ninu ọla a, ni ọmọ pandọrọ ngbo si.

E. A. OLUYẸLE BRIGHT,

---

## IROHIN ẸGBẸ ṢOKI.

Awọn Ẹgbẹ Irãwọ Onigbagbọ *Christian Helping League*, lọ da ẹka Ẹgbẹ 'lẹ ni Ifakọ Agege ni ọjọ kẹjọ oṣu yi *Sunday 8th October*. A dupẹ lọwọ Ọgbẹni wa C. Collins Clle (Karaole) ti o gba nwọn towọ tẹsẹ si ilerẹ ti o si se ase nlanla fun nwọn ki Ọlọrun ko ma jẹ ki apo gbẹ o. *Amin*.

Atun juba Ọgbẹni wa W. A. Dawodu loni Motor, ti o fi *Motor Bethlehem* jinkí nwọn Nigbati *Motor* yi fẹ de Ifakọ oku sọna, ni kankanṣi ni Mr. Tohmipson atukọ *Motor* na sarewale pẹlu *Bicycle* o si pada ni nkan wakati kan pẹlu *Motor Dodge* kan; o ṣe wahala titi ṣugbọn ko ri pa kan sa. O kuro ni Ifakọ ni agogo mẹfa alẹ Nigbati o di agogo mẹjọ abọ ha ri *Motor Dudje* mẹta ti W. A. Dawodu fi ranṣẹ gbogbo rẹ ni awọn Ọmọ ẹgbẹ si kun sibẹ o ku awọn diẹ ti ko r'aye; *Motor* wọnyi de ile ni agogo mẹwa abọ alẹ *Motor* kan si tun para lati lọ ko awọn iyoku.

Adura wa ni pe ki Ọlọrun ki o bukun ile ati ọna Ọgbẹni wa yi *Amin*.

Tani lawa o ni baba ṣai a ni baba Karaole Baba wa, W. A. Dawodu Baba wa.

J. Adekunle John
Akọwe Ẹgbẹ.

---

## OPEN LETTERS. No. 2.

To the Town Engineer,
Lagos Town Council,
Catholic Mission Street,
Lagos.

Sir,

Permit me, through this medium to bring to your notice the awful and deplorable state in which some public thoroughfares to wit, Upper Moloney Bridge Street, Idoluwo Street, Isalẹgangan Square, Okepopo Street, Koilọ Street, Branco Street, Vincent Street, find themselves consequent on the present inclement weather: it goes without saying that houses situate in these parts of the town cannot be immune from dampness with all its concomitant evils, characteristic of the precarious weather such as we are now experiencing: it is to be supposed the people in these vicinities are not behind in contributing their own quota to the public Revenue by way of the payment of taxes, in one shape or another.

It will be relieving the situation, Sir, if amidst your multifarious duties—your attention is centred on each of the streets with a view of improvement

I am sure, the inhabitants thereof will not be too loud in their appreciation of so Timely an act.

May I be on the tenter-hooks?

EKO AKETE.

## *KILOPO? 2.*

LATI ỌWỌ, *EDITOR* EKO AKETE.
[ A ko gbọdọ da Iwe yi tẹ lai gba'ṣẹ.]

### ỌMỌ NI 'O JOGUN.

Ti a ba bere lọwọ awa Yoruba pe kini a ndu pupọ lati ni lẹhin owo, a o dahun pe ọmọ ni: otitọ leyi, o si fi ara han fun ẹnikẹni pe bi enia ko ba bi 'mọ, bi oti wu ko ni alumọni aiye yi to, ko ni si itẹlọrun fun irufẹ ẹni bẹ: ọrọ ọmo jẹ ribiribi larin wa tobẹ ti a fi sọ orişi aşọ kan ni "Ọmọ ni 'o jogun" ti gbogbo enia nsure si lati ra, lakoko kan. A le sọpe ipo ọmọ rẹhin diẹ, nigbati a ba ranti owe ti a npa nigbamiran pe, "Owo l' ẹgbọn Ọmọ l' aburo:" şugbọn sibẹsibẹ, eyi ko sọpe ipo ọmọ-bibi jẹ ipo ti o şe ainilari larin wa: Ẹ jẹ kafi apẹrẹ kan yẹwo: bi olɔwo kan baku nilu, ibere kini ti a o kọ bere nipe, "Şe Lagbaja f' ọmọ silẹ?" eyi tunifihan ni pe ọran ọmọ "ja-nto-ja-nto lo jẹ larin wa: Şngbọn ewu to wa fun obinrin ti ko ba ti bimọ ni ile ọkọ nipe ko ma nu ara rẹ ni "damu" egbogi lati bimọ: anu şeni pe nipa ọna bayi, inu ọpọlọpọ obinrin miran ti "sepọn," tobẹ tojẹpe awọn miran ti wa "koran" lẹhin ajo irufẹ eyi: nigbamiran ti ajo ba pọju, adaunşe miran a tilẹ sọpe ki obinrin miran gbe ọmọ ẹran pọn, pẹlu ileri pe, ti ọmọ ẹran na ba nke "Bẹ," laipẹ, irufẹ ẹni bayi yio lovun !!! nipa ọna bayi, a ti tan ọpọlọpọ obinrin jẹ, a ti fun wọn ni ironu kun ironu, a si ti sọwọ wọn dilẹ! Ẹwẹ, a tun ri pe jijẹ ogun iloyun lai-mọniwọn nmu obinrin miran bi "DANI" "dani-dani!" (A ko sọpe awọn to ba njẹ DANIEL ni ọrọ yi nbawi, o, ọrọ lolọ bẹ) Ki Edumare gbani ninu idamu ọkan bayi, AŞE: a kole ba awọn obinrin ti o nşajo ati bimọ wi, şugbọn o yẹ ka ma şe mẹlọ-mẹlọ fun egbogi ajẹju, ti yi o mu awa papa jẹbi ohun ti a nwa; A mọ pe awọn afori obinrin miran wa ti nwọn nwipe wọn ko leşe wahala omọ-bibi; irufẹ awọn bayi gbagbe pe bi iya won ba sọ bayi ni, awọn papa koni le wa lori ilẹ. Anu sişe ni pe ọpọlọpọ awọn ọdọ obinrin ti nwọn ti wọ ile ọkọ, lo wa nisisiyi ti wọn ya agan!!! ki onibu Ọrẹ maşai fi oju anu re wo irufẹ awọn ẹni bayi. *Amin.* Ki Ọlorun si da ti awọn ti wọn ni si. *Amin.*

Agba dọwọ awọn aya wa, ti nwọn njẹ egbogi ati bimọ wọmuwọmu lai-boju w' ẹhin,—Kilopo?
KI ỌLỌRUN MA FI ỌLỌJỌ RANTI.

### ẸRU OWO.

Owe wa kan sọ pe. "Aiye la b' owo:" şugbọn sibẹsibẹ a nri awọn ẹlomiran ti a fi ẹbun yi fun ti wọn si sọ ara wọn di ẹru-owo nipa iwa wọn: fun irufẹ awọn ẹni bayi, owo "di orişa o di ohun akunlẹ bọ:" ipa lo le fi ri aşọ atata kan lara wọn: a ko wipe ki nwọn ma lo aşọ alarabara tabi ki wọn ma "gun-wo-lodo" nipa aşọ wiwọ. Nigbagbogbo ni nwọn ma nwọ aşọ ti 'o-bu-enia," aşọ ti ẹgbẹ tabi ọgba wọn ko jẹ wọ: ipa sin ni onjẹ atata fi le wa lori *table* won; bẹni ohun ti a ba jẹ lo nba ni lọ, eyi owo ẹni ọhun ko si ni şe mu jade fun lilo ohun ti o yẹ ipo wọn: şugbọn asẹhinwa asẹhinbọ, ti o ba di "obiri aiye pada" ti ayipada ojiji bade, yala nipa iku ni o, tabi ọfọ nla kan, ni nto ye awọn irufẹ enibayi pe ko si mimọşe kan lọwọ enikẹni bikoşe lọwọ ALLAH!!! gbogbo wahala hiha owo m' ọwọ, a si jasi asan nikẹhin:—Kilopo.?

### "IDI-ILẸKẸ."

O jẹ ohun to wọpọ ni ode wa isisinyi lati ma yi ede po ibajẹ yi si pọ tobẹ to jẹ pe a sofin lakoko kan ki gbogbo orin alufaşa bi "Gbe mi si bebe" "Lagidigba, ni bebe" dinku larin wa nilu: şugbọn sibẹsibẹ a nri awọn "ala-febi-pa" obinrin miran ti oju ki iti lati ma pe ara wọn ni "Idi ilẹkẹ" ede niyi, ẹ jare? Bı ko şe ede panşaga! obinrin miran ko ni işẹ kan ju ki o ma fi gbogbo ọjọ aiye rẹ ma *fry* ara lọ, fun iwa aitọ eyi si jasi opo ọpọlọpọ fun ẹlomiran, nwọn si gbagbe pe adanu nla ni esu irufẹ iwa bẹ lẹhin-ọla: nigbati a ba nro nigba gbogbo pe gbogbo irufẹ iwa bayi "iyẹpẹ ni" gẹgẹ bi ede awọn miran, o yẹ ki pẹlẹpẹlẹ to awọn ọmọge wa lati dẹkun ati ma tẹlẹ "koya,-koya" ẹwa oju akara ni ogo asan obinrin miran; nigbati obinrin to ti npa ara rẹ lopo lati ma şe fefe, fun iwa aitọ ba di "Ọkẹgẹ" nikẹhin, yio wa di wlpe "bi idı ba bajẹ, ti onidi ni nda" Kilopo.?

### "IBANUJẸ-SORI-AGBA-KODO:"

Aiye wa kun fun croro dapọ mọ oyin tobẹ ti a fẹrẹ le ma sọ nigba miran pe kini "komi" wiwa s' aiye? Şugbọn ti a ba si ro lọna keji pe ayọ ayọju ma njẹ ki akere fi itan şẹ, yio wa ye ni pe ayọ ati ibanujẹ jẹ tẹgbọn-taburo fun rere wa l' aiye. Sugbon a nri nigbamiran pe ohun ti agbojule pe ko tẹni lọwọ ndi ofo mọ ni loju, nipa bayi ibanujẹ nlà lo jẹ fun ẹlomiran ti ko ba lọkan: eyi nkọ ni pe ki opo wa ma mọ niwon fun ati şe ohunkohun, a sa mọ pe "ajo aşeju mu adıẹ fọ ẹyin" nitorina maja-masa ni aiye nfẹ: yiyi l' aiye nyi:—Kilopo?

### SCRIPTURE COLUMN.
(BY M. BANKOLE FADIPE.)

Man's goings are of the Lord; how can a man then understand his own way. Prov. 20. 24.

I make peace, and create evil; I the Lord do all these things. Isai. 45. 7.

But Zion said, the Lord hath forsaken me, and my Lord hath forgotten me. Can a woman forget her suckling child, that she should not have companion on the son of her womb? Yea, they may forget, yet will I not forget thee. Isai. 49. 14, 15.

Rejoice not against me, Oh mine enemy: when I fall I shall arise; when I sit in darkness, the Lord shall be a light unto me. Micah 7.8.

## KINI IWỌ ṢE FUN U.?

Ohun ti o mu ni kọ ibere ọrọ ti o wa ni oke iwe yi ni pe nipa itọrẹ-anu tabi ọrẹ ti olukuluku, ẹniti Ọlọrun ba fun ni owo aiye yi ngbero lati fi ta ilu rẹ lọrẹ. Iba ṣe loju ẹmi ara-rẹ tabi lẹhin igbati o ba gbọ ti o ba si rẹ. Itumọ ibere wa ni pe, kini iwọ ngbero lati ṣe fun ilu rẹ?

Nigbati a ka itan ilu awọn oyinbo nwọn ko jẹ ẹni ẹhin nipa eyi. Ọna pupọ li o wa ti nwọn si fi nta ilu wọn lorẹ ki nwọn to pẹhinda. A o darukọ diẹ ninu wọn papa nipa Ile Ẹkọ awọn ọmọde laimẹnu kan awọn ti o fi ọpọlọpọ owo silẹ lati kọ Ile-Alarun tabi Ile Ọmọtikoniya, ati oniruru ẹbun ti a ko le ma darukọ wọn ninu iwe yi.

Ọpọlọpọ Ile Ẹkọ ni o wa larin wa l'Eko, mo si ro pe awọn Oniwasu ti igba lailai ni o da wọn silẹ pẹlu awọn ara ilu ti o wa lakoko na, ki awọn Ijọ to ma tọju wọn, ko si Ile Ẹkọ kan ti o jẹ pe nipa ẹbun owo ẹni kan li a ṣe da silẹ. A ko fi agbara pe ẹnikẹni ki o ta ilu rẹ lọrẹ, ṣugbọn fun ire iran ti o mbọ lẹhin ọla ni a ṣe nke pe awọn olowo arin wa pe ki nwọn ma gbagbe iṣẹ wọn si Ọlọrun ati si enia. Ẹ jẹ ki a mu ohun ti a nsọ lati inu ilu awọn Gẹsi nipa awọn ti o fi owo ati ilẹ wọn fun kikọ Ile Ẹkọ ni iranti orukọ wọn lẹhin ti nwọn ba ti fi ilẹ bo ara bi aṣọ:—

(1) Kini "*Eton College*" ma jẹ ti o ma fi gbagbe Henry Kẹfa Ọba England, ẹniti o fi owo ara rẹ kọ Ile Ẹkọ Giga ti a npe ni *Eton College*."

(2) Kini "*Rugby School*" ti ṣe le gbagbe orukọ "Laurence Sheriff" ẹniti o fi ilẹ ati owo silẹ pe nigbati on ba ku tan ki nwọn fi owo yi kọ Ile Ẹkọ si *Rugby*-Ilu ti a bi i si.

(3) Kini "*Harrow School*" ma jẹ ti o le gbagbe "John Lyọn" ẹniti o lawọ-Agbẹ kan ni Ilu "Preston" ti o ṣe wahala lati kọ Ile ẹkọ yi, awọn enia nla ni o ti kọ ẹkọ ninu rẹ, nwọn ko si ni iye.

(4) Kini "*St. Paul's School*" ni ilu Oyinbo ma jẹ ti o le gbagbe "John Colect" ẹniti o fi owo silẹ lati kọ Ile Ẹkọ yi.

Diẹ ni a mu lati inu ọpọlọpọ apẹrẹ. Nitori ki awọn ẹni nla wa ma le run lori ilẹ aiye ati fun ire awọn enia ni a ṣe sọ pe ki awọn olowo ilẹ wa yẹ aṣaro wa ọsẹ yi wo.

Ṣugbọn a dupẹ lọwọ ẹni wa kan ti o nran awọn ọmọde meji lọ si Ile Ẹkọ giga fun ọdun mẹta tabi mẹrin ni ireti pe bi nwọn ba mọ ẹkọ wọn tan ki nwọn ma ṣe iṣẹ Oluko, a ko ni darukọ rẹ, ṣugbọn ọpọlọpọ wa le fi oye mọ oninure kan ti o wa ni Ile Elerin loke Olowogbowo, ki Ọlọrun ma jẹ ki a ma fẹ iru enia bayi ko larin wa, bẹ na ni akoko kan ti Ọbọrọwọ bi onilajẹ yi ra Duru (*Harmonium*) kan fun Il[e] Ẹkọ eyiti o npese ọmọ meji fun lati ma [...] olukọ ninu rẹ.

Fun awọn ẹni wa ti Ọlọrun fun, ṣugbọn [...] nwọn nkọminu ni a fi ọrọ iyanju ti Ọgbẹni Hall, *Bishop* kan ni ilu Oyinbo kọ si Ọgbẹni Sutton ṣe apẹrẹ fun. Gbọ bi o ti wi lede Gẹsi:—

"*I ask leave to hasten your pace a little, and to excite your Christian forwardness to begin speedily what you have long and constantly vowed. You would not but do good; why not now? I speak boldly, the more speed the more comfort; neither are the times at our disposal nor ourselves. How many have meant well and done nothing, and lost the crown with lingering? Say not to-morrow I will give it thou now have it, for thou knowest not what a day may bring forth. It hath been an old rule of liberality, 'he gives twice who gives quickly;' whereas slow benefits argue uncheerfulness and lose their worth.*

*Who lingers his receipts is condemmed as unthrifty; he who knoweth both hath said, 'it is better to give than to receive.'*

*If we are on the same spirit, why are we hasty in the worst and slack in the better? Suffer you yourself, therefore, good sir," for God's sake, for the Gospel's sake, for the Church's sake, for your soul's sake, to be stirred up by these few lines to a resolute and speedy performing of your worthy intentions.*"

"Mo bẹ ọ ki o ma jafara lati ṣe ohun ti o ngbero lọkan rẹ, mo si tun bẹ ọ ki o ṣewere bi Onigbagbọ lati ṣe ohun ti o ti jẹjẹ lọkan rẹ lati ṣe mo ri i pe o ntẹ ṣe ohun rere; kini ṣe ti o fi nfalẹ? Tọkantọkan ni mo fi mba ọ sọrọ yi, bi o ba ti ṣewere si bẹ na ni o ma ri itunu rẹ gba si; gbogbo akoko wa lọwọ Ọlọrun, ọwọ Ọlọrun ni awa papa si wa pẹlu. Ẹni melo-melo ni o ti fẹ ṣe rere ti nwọn ko si le ṣe e, ti nwọn si ti sọ ade—ogo wọn nu nipa ijafara; Ma ṣe sọ pe o di ọla ki o to fi ohun ini tọrẹ nigbati o jẹ pe o ni nkan na lọwọ nisisiyi, bẹni o ko mọ ilẹ ti o ma mọ ọla. Awọn kan ni o ma nsọ wipe, "ẹnikẹni ti o ba fi nkan tọrẹ lakoko, o dabi eni pe igba meji ni o fi nkan na tọre, ati bi eni ba fẹ fi nkan tọrẹ ti o ba si nfa tikọtikọ, o dabi ẹni pe ko telẹ ọkan rẹ, chun ti a fẹ ki tọrẹ na a si sọ adun rẹ nu Ẹnikẹni ti ko ba fẹ ma na owo rẹ, on ni a ma npe ni awun enia. Ẹnikan ti o ni oye lori sọ wipe, o ni ibukun lati fi nkan tọrẹ ju lati gba lọwọ enia lọ? Bi a ba ni irufẹ ẹmi bayi, kini ṣe ti a[...]

...nia ma nya lati şe ohun buburu, ti o si ma ...fa tikǫtikǫ lati rere? Nitorina, iwǫ alagba 'ati ...ni rere, mo bę ǫ nitori Ọlọrun, nitori Ihin Rere, nitori Ijǫ enia Ọlọrun, nitori igbala ...kan rę, ję ki awǫn orǫ dię ti mo sǫ yi wǫ ...nu ǫkan rę lǫ, ki o si mura giri lati şe ...ohun ti o ti ngbero lǫkan rę lat şe."

A fi ǫrǫ Ęni Ọlọrun yi le nyin lǫwǫ, nitori lǫkan wa ko si aşadanu ninu ǫrǫ yi, o ...si wǫ to gbaję nipa ǫrǫ ti enia le sę fun ...enikęni ti o ba şiyemeji lati şe ore fun ilu rę.

ELETI ỌFẸ.

## THE "AJENIFUJA" SEWING MACHINES.

These Machines are German Manufactured. Constructed of the best materials and skilful workmanship, very splendid in appearance, quick action and noiseless. No confusion, simple to thread, easy to operate. Durability Guaranteed will last almost life time, call for one at ORI-ADE STORE 97 & 109, Broad Street Lagos, Needles, Shuttles, etc., etc. in stock. Prices on application.

VIDAL R. COLE,
*Sole Agent.*

## "OŞEWỌNI!" (FAIR WARNING)

Ọgbęni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aşę ǫdǫ Ijǫba *Nigeria*, nta orişirişi ǫja ni Gbanjo, nile Gbanjo rę ni 2, Isalęgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilę pęlu.

Awǫn ǫjǫ ǫja-tita ni iwǫnyi. Monday, ati Thursday, lagogo męta ǫsan. Saturday, lagogo męsan arǫ, lǫsǫsę. O ntete san owo ǫja fun enia. Mu ǫja rę lǫ si bę.

N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

J. F. SICK ati Awǫn Ęgbę.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street*) EKO.

Awǫn Oyinbo onişowo yi nranşę MAŞINI-ARANŞO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' olǫwǫ ati t' ęsę ni owo to rǫju: a le fi iye-owo won han ęnikęni to ba lǫ si Ile-Owo yi.

Nwǫn mura tan lati şe Adehun pataki pęlu ęnikęni to ba fę ranşę Mejila tabi ju bę lǫ ninu MAŞINI na:.

Awǫn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilękę alarabara, Nwǫn si nranşę (*Cemet*) ati panu-kikǫle to nipǫ, ati Ęja Abǫmafǫ ati Orişirişi ǫja.

Ilękun Ile awǫn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fę lati lǫ ba wǫn sǫrǫ AŞIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.

## ILE EGBOGI IŞẸ OLODUMARE.

A şi ile Egbogi kan ti a npe ni Işę Olodumare si Ọja Ọbun Eko ni ile kęta si Iga Oloye Aromirę. Nibę ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan,

Ibaşe fun Orififo, Inurirun, Ęda, Inarun, Aran Kinnişa, Ikǫ, Ipa, Ọręrę, Ọşę Egbogi, Egbogi Oju, ati awǫn Oniruru ti a ko le to sihin tan.

Rin de bę ki o wo ǫ. Irohin ko to afojuba.

Iwǫ ko tilę gbo oruko rę ndan?

Işę Olodunmare !!!

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

## ILE OWO-ỌJA RIRANŞẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbęni S. B. VINTURA, Aşoju awǫn Ęgbę Oyinbo yi mura tan lati ranşę awǫn Ọja bi i *Herbadashery* eyini ni Şęda, Onini, Owu-Şęda alarabara, Ohun-Flo awǫn Aranşǫ, ati oniruru Ọja bawǫnni lati ǫdǫ awǫn Oyinbo rę ni Ilu Oyinbo ni owo pǫ ǫ.

Ọgbęni na si ni awǫn Akętę (*Fell*) Bata Funfun ati awǫn nkan miran daradara pęlu ni tita ti owo wǫn ko ta enia laiya.

Ę lǫ danwo ni Ile-Owo rę ni Ita Tinubu, t' o kǫjusi Kǫtu, l' Eko.

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun lati Ilu Germany fun tita: awǫn nkan Awo Abǫmafǫ, Cement, Akara, ati Ọpǫlǫpǫ Ọja miran.

Ę lǫ de ibę, Igbo-Akan 'mǫpa ni ohun to ni.

Bi ǫ ba fę ękǫwe si i, Number Apoti-Iwe rę ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374: Number fifi-ęrǫ manamana ba a sǫrǫ (*Telephone*) ni 243.

# Advertisements.

IPOLOWO OJA.

—:o:—

## ALASE LEATHER FACTORY.

### "ILE ALAWO."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣowọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALAṢẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.

—o—

## READY.

**"Church and Politics."**
**(A Lecture)**

OR

THE DUTY OF THE CLERGY TO THE LAITY.

BY PROF: DENIGA.

SOLD at 24 Williams Street, Lagos.
3d. a copy.

AWON ẸGBE OYINBO ONIṢOWO TI A NPE NI
E. H. STEIN ARA HAMBURG.
NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn oniṣowo ti Ilẹ Enia Dudu, awọn ti nranṣẹ Oja fun enikẹni to ba fẹ'ibaṣe Oja ti Ilu Gẹsi tabi ti awon Ilu oyinbo miran ta o wa lagbede *England* ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Oja bi Epo tabi Ekuro ti a ba fi ranṣẹ siwọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Kosi ewu kankan ni fi fi Oja-koja ranṣẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi ṣowo lọ tabi ki o kọwe si Aṣoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-iṣẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-ifi Oja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) L'Eko.

Ẹnikẹni le kowe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn oyinbo oniṣowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8 TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni—
8 TINUBU SQUARE, LAGOS.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.